**LAKAYE ỌRỌ**

Ẹniti o ba fa ọwọ papan sẹhin, o korira ọmọ rẹ, ṣugbọn ẹniti o fẹ ẹ, a ma a tete na a.

Ẹniti Oyẹ kọ fun a ma a gan ọmọnikeji rẹ, ṣugbọn eni Oyẹ a pa ẹnu rẹ mọ.

Ọna kan wa ti o da bi ẹnipe o dara fun enia ṣugbọn o p i n rẹ ọna iku ni.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Owe**

Ẹnyin Agbagba, ẹ ba wa tun ilẹ wa ṣe, ẹ ma jẹki o bajẹ, ẹnu ni abẹrẹ fi ntun aṣọ ṣe.

VOL. VI No. 358 MONDAY NOVEMBER 26 — DECEMBER 2 1962 KOBỌ MEJI (2d)

# MAJA GBERO LATI ṢE IJAMBA FUN IJỌBA

**Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejilelogun o ṣ u yi ni Dokita Ọladipọ Maja ti o ti jẹ ọkan ninu awọn Ọdaran ti Ijọba mba ṣẹjọ, ti nwọn si ti gbegile ẹsẹ t i r ẹ wipe, ko lẹsẹ lọrun mọ, sọ niwaju Adajọ kotu giga Eko, Ọgbẹni G. S. Sowẹmimọ, wipe on ti ṣe eto lati ṣe ijamba fun Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria l'Eko ninu Ipade ti nwọn ṣe ninu oṣu kejọ (August) ọdun ti o kọja yi.**



**Aworan ti a nwo yi ni ti Dokita Maja ati ọgbẹni John Lynn, 'gbakeji Ajẹlẹ Amojuto ti iṣe Ọlọpa Apapọ Ijọba Naijiria, ti iṣe O l o r i awọn Ọlọpa-inu.**

**Dokita Maja tun ṣe alaye niwaju Adajọ pe, nigbati on pari gbogbo e t o na on fi ọrọ na han Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ n i n u ile rẹ ni Ibadan.**



*Alhaji S. O. Gbadamọsi*

**Lẹhin ti o ti sọ gbogbo ohun ti o fẹ sọ tan patapata, ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ wa bẹrẹsi b e r e ọrọ lọwọ Dokita Maja bi o ti ṣe lọ si ile Awolọwọ ni Ibadan on ati Alhaji S. O. Gbadamọsi ati ohun ti o sọ fun Oloye Awolọwọ ati bi Dokita Maja ti ṣe gba ẹdẹgbẹrin ponun (£7,000) lọwọ Dokita Nkrumah ati ohun ti o fi owo na ṣe.**

*Awolọwọ:* Njẹ mo ba ọ sọrọ nipa ohun ọsẹ?
*Maja:* Rara o.
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti pe Alhaji S. O. Gbadamọsi lo mu ọ wa si ile ọdọ mi?
*Maja:* Bẹni
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti ọrọ ti Dokotri sọ fun mi, ti mo sọ fun ọ niṣoju Gbadamọsi.
*Maja:* Bẹni, mo ranti.
*Awolọwọ:* Mo sọ fun o wipe o ti pe Dokotri lati Jos, bẹni o si san owo ọkọ rẹ alọ ati abọ.
*Maja:* Bẹni, emi ni mo san an.
*Awolọwọ:* Njẹ o se iranti wipe ni ile rẹ ni Dokotri sun ni ọjọ na?
*Maja:* Bẹni.



**Oloye H. O. Davies**

*Awolọwọ:* Njẹ o ranti wipe o ba mi sọrọ lori bi eto awọn Oṣelu se rilọ ni Naijiria nisisiyi?
*Maja:* Bẹni.
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti pe gbogbo awọn Olori ẹgbẹ Oṣelu ni o bu ni ọjọ na?
*Maja:* Bẹni
*Awolọwọ:* Bẹni o sọ fun mi ni ọjọ na pe o ti se eto lati se ijamba fun ile Igbimọ Ijọba Apapọ Naijiria ninu ipade wọn ninu oṣu August?
*Maja:* Ohun ti mo sọ ni pe.
*Awolọwọ:* Mo sọ fun ọ wipe Dokotri lo sọ fun mi.
*Maja:* Rara o.
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti pe o sọ fun mi pe o ko ni igbẹkẹle ninu ibo?
*Maja:* Bẹni.
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti pe o fẹ ki Dokotri lọ ko awọn kan ni oke Ọya ni Ghana tabi Guinea?
*Maja:* Nko le ranti iyẹn mọ.
*Awolọwọ:* Bẹni, iyẹn ko ṣe ranti. Njẹ o le sọ fun ile-ẹjọ, ohun ti o wa ṣe ninu ile mi? Tabi mo kọwe si ọ? Kini idi na ti Alhaji Gbadamọsi fi mu ọ wa si ile mi?
*Maja:* Bẹni, Nigbati mo bẹrẹsi bu gbogbo awọn ẹgbẹ Oṣelu ni Gbadamọsi wa sọ fun mi pe ọrọ na bi ọ ninu.
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti nisisiyi pe mo sọ fun ọ nisoju Gbadamọsi pe, Dokotri sọ fun mi wipe o nmura nigbana lati ṣe ijamba si Ile Igbimọ Apapọ ninu ipade wọn oṣu August 196·?

**IPADE**

*Maja:* Bẹni, O sọ fun mi.
*Awolọwọ:* Nje Gbadamọsi ko sọ fun ọ wipe emi Awolọwọ fi ẹjọ rẹ sun Baba rẹ ninu ipade kan ti a sepọ, wipe ohun ti o fẹ se yẹn ko dara?



**Adajọ Agba Ṣowẹmimọ**

*Maja:* Bẹni, ootọ ni.
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti pe, mo sọ fun ọ pe, nitotọ o ki iṣe ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre, ṣugbọn ti o ba ṣe ohun ti ko dara ọmọ rẹ Maja yio kan ẹgbẹ Afẹnifẹre.
*Maja:* Nko le se iranti yẹn mọ.
*Awolọwọ:* Nje o se ranti wipe mo bi ọ lere pe, bi o ti le fẹ se



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**

ijamba fun awọn enia kan, ese ti o fi fẹ ki nwa ṣibẹ?
*Maja:* Otitọ ni, o wi bẹ.

Lẹhin eyi ni Oloye Awolọwọ bere lẹta kan ti Dokotri kọ si Maja ati eyi ti M a j a da pada si Dokotri. Maja sọ fun Adajọ pe, on ti fa lẹta na ya, ṣugbọn ki o to wi bẹ tan, Awolọwọ ti yọ ẹda lẹta na jade.
*Awolọwọ:* N i n u lẹta na ni Dokotri sọrọ kan ti ẹ dijo sọ?
*Maja:* Ko ri bẹ.
*Awolọwọ:* Njẹ o ranti pe o d'esi lẹta na pada?
*Maja:* Otitọ ni

Lẹhin eyi ni Oloye Awolọwọ yọ ẹda lẹta na jade Adajọ si gba iwe na ka lọwọ rẹ.

*Wo oju ewe kẹjọ*

# Adamọdi Olori Ile-iwe kan wẹwọn

ASABA – Lẹnu lọlọyi ni Adajọ ...to Ijọba Ibilẹ Asaba ju Ọdaran kan, Raymond Eghagha, ẹni ọdun mẹdọgbọn, ti o ngbe Cemetery road, Warri, si ẹwọn oṣu mẹfa fun ẹsun jijiti ti awọn Ọlọpa mu u fun.

Ẹjọ ti Ọlọpa ti o ba Ọdaran na sẹjọ ro niwaju Adajọ ni pe, Ọdaran na ṣe ikede si inu iwe Irohin, pe on da Ile-ẹkọ Ise imọṣẹ (School of Technology) silẹ, o si bẹrẹ si gba owo lọwọ awọn ọmọ lati pọnun mẹdọgbọn titi de adọta pọnun (£25 - £50) lọwọ enikọọkan.

Lẹhin ti awọn ọmọ wọnyi ti fi owo na ranṣẹ tan, Ọdaran na kọwe si wọn, nigbati awọn ọmọ na si de si Onitsha ti nwọn ri i pe ko si Ile-ẹkọ kan ti o njẹ (Eastern School of Technology) ni awọn ọmọ yi ba wa si Tesan nigbati awọn si mu Ọdaran na, awọn kan wa gba ibiro rẹ, ṣugbọn Ọdaran na salọ si Abraka ni Ipinlẹ Iwọ-Oorun, awọn ri i awọn si mu u lọ si Asaba ni Tesan awọn Ọlọpa.

Ọlọpa na sọ wipe nigbati o di agogo mọkanla koja ogun iṣẹju (11:20 a.m.) ni ọsan gangan, Ọdaran na fọ ojurese Tesan Ọlọpa, o si salọ. Bi Ọlọpa ti o wa ni ... ti nle Ọdaran na lọ o wọ inu igbo kan, ṣugbọn bata ti o wọ ko jẹ ki o le sare, ni Ọlọpa na ati awọn ọmọ Ile-Iwe ti o wa si ... ba mu Ọdaran na, awọn si tun ti mọle si Tesan.

Nigbati adajọ ṣe Ọdaran na lere, ti o si rojọ, ti o si gba wipe on jẹbi ẹsun na, ṣugbọn ẹsu lọ tan on huwa ... ni Adajọ ba ni ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹfa lafarabata.


## KERE O! KERE O!!

WA SI ILE–IṢE

**"Iranlọwọ Oluwa Furniture Maker"**

nibiti a gbe nṣe orisirisi awọn ohun ọṣọ ile bi Aga joko, Ibusun Onitimu timu, Konbodu onje Konbodu aṣọ, Tabili onje ati ti ikọwe.

Eyi nikan kọ, a tun ngba agbakọ ile, a si ntun ile ṣe, a si nkọ patako wa fun eiti o ba nfẹ. Irohin ko to afojuba, wa si ile-iṣe wa ki o wa wo.

ILE–IṢE:-
77, HERBERT MACAULAY STREET,
EBUTE METTA


## National Bank of Nigeria Limited.

CHRISTMAS SHILLING FUND – DECEMBER, 1962.

Depositors in the Christmas Shilling Fund are hereby reminded that in accordance with the regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday, 3rd December 1962.

Withdrawals can only be made by the depositor in person and on production of his pass book. In the case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, such applicatoin to be accompanied by the depositor's pass book, for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on the 31st December, 1962, and depositors who fail to withdraw on that date cannot do so untill next Christmas.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the depositer's surnames on the date shown hereunder and the depositors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to untill Monday, 10th December, 1962.

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| | | A | Monday | 3rd December, 1962. | |
| B | TO | H | Tuesday | 4th | „ „ |
| I | „ | N | Wednesday | 5th | „ „ |
| | | O | Thursday | 6th | „ „ |
| P | „ | Z | Friday | 7th | „ „ |
| A | & | O | Saturday | 8th | „ „ |

For the year 1963, deposits will be taken as from Wednesday, 2nd January, 1963.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER.


## KERE O! KERE O!!

KURANI L'EDE YORUBA

TI DE

A nta Kurani Ọgbọn-Ẹsẹ ti a ṣe ni Larubawa ati itumọ rẹ l'ede Yoruba. O wulo fun enikeni.

**Price: 25/- Postage 1/6d**

Iwe Egbogi Iwosan Atayebaiye, o kun fun Awure, a le ri Itumọ Ala ati ohun t'oba tumọ ninu Odu-merindinlogun ninu iwe kanna 10/6d Postage 9d

*TETE FI OWO TIRE RANSẸ SI:*

ESAN KOGBOGUN SERVICE.
8, Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria.



## KERE O! AKIYESI PATAKI!!

Awa na le jeri wipe Ojulowo Iwunbaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, awa na nlo won ... (Ankara Ghana) pẹlu ... ninu gbogbo orisirisi Egbogi ... Ila Naijiria.




Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹ na ni awọn ... gbogbo Ilu Eko, Irohin ti o wa lọnu gbogbo enia l'ọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi ṣe ọrọ ali ọrin larin ara wọn ni wipe Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti awọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ Ojulowo ... ati afọwọṣe fun awọn "JEDIJEDI" bi o ti wa ki ọjọ le pẹ to ... awọn le fun ... tabi ṣe iṣẹ fun gbogbo awọn ti amọdi tabi Ilu. Igbe ... tabi aiko ... Inu ... ara wiwu, Ẹsun, Ehin didun, Oju akan, tabi aiko ... pẹlu "Wipe" ... ni ... ti nwọn ba nlo Egbogi LEOPILLS ... ti ... ojo'ṣe lara enia nipa ... di otun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA L'OGUN ORO, IJAFARA SI LEWU PELU! (POSTAGE 1/9d)

**IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:-** Igo nla ṣile mẹta abọ (6/6d) pere ni, Igo kekere ṣile mẹta abọ (3/6d) pere ni.

Bere Ojulowo Egbogi mi yi fun orisirisi Amọdi ti o ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
8, Palm Church Street, P. O. Box. 333 Lagos Nigeria Phone 22878, ati pẹlu ni Ṣọbu awọn arabinrin Mrs. C. O. Babajide near Health office Ibadan ati ni Abimbola Medicine Store B29 Okesha Street Ilesha, Bisade Medicine Stores, British & Foreign Medicine (Dealer) S. W. 6/458 **AGBOKOJO STREET IBADAN N**

**AKIYESI:-** Ri daju gbangba wipe Ṣọbu ti awọn nta la gbe ranṣẹ lọ, bi bẹ kọ awọn elomiran yi fi EBU jọ ta Adamọdi tabi orisi omiran fun ọ o maṣe gba rara o.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI OSESE DE TI NWỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TỌNIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN EGBOGI AGBALAGBA ỌKUNRIN ATI OBINRIN GBOGBO




Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣe ṣiṣe ti o ko ba jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de bi kan lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ko ba ṣiṣe daradara erọ Ẹmi (Breath) inu ko ba gunle daradara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJẸ" fun wọn ni ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori re (age) ba ti kọja Ogbọn odun lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 TINUBU STREET LAGOS, PHONE:- 20278.
**Waterloo Medicine Stores,**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigerian, (Ọja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO

# Oluwa Ọlọrun nikan ni olugbala gbogbo enia

Lati Ọwọ ONIJANMAAWURA Eko

Ekute to fa'kọ silẹ ti o njẹ ọbẹ ni ọrọ rẹ ọrẹ mi, Joseph Iddo-Oro. Alaye Bibeli ni a ni ki a ṣe fun ara wa, kini ẹkẹ oebu wa de inu ọrọ Ọlọrun, kini "Ogun imarun ati "Ile iwe Ọlaparun" wa de inu ọrọ Ọlọrun? O wun mi lati fun ọ ni esi ọrọ rẹ, ṣugbọn Bibeli sọ wipe, maṣe da aṣiwere lohun gẹgẹbi aṣiwere rẹ, ki iwọ psapa na ki o ma ba dabi rẹ, Owe 26 ẹsẹ 4.

Ẹri mẹtala ni mo fi fesi ọrọ ti ọga rẹ tẹ jade. Ọrẹ mi, o tako mẹrin ninu rẹ, njẹ mẹsan yoku nkọ? Joseph, o da mi loju wipe otito ni yio leke irọ. O fesi wipe ọrọ awọn keferi ni o wa ni ori 43 ninu iwe Woli Isaiah ti mo ti yan ẹri kan jade. Njẹ ọrọ inu Bibeli ha je fun awọn ẹya kan bi? Njẹ ọrẹ mi nibo ni a ti da oruko awọn Keferi ni Isaiah ori 43 ti mo yan ẹsẹ 10 ati 11 rẹ? Jọwọ ka Bibeli rẹ daradara ki o to ma fun mi ni esi.

Arakunrin, ti mo ba fi ododo ati imọ han ọ ti o ba kọ, o ha se ki o tun lọ fa nkan miran lẹsẹ! Njẹ gbogbo agbara laiye ati lọrun ni a ti fi fun Jesu? Agbẹdọ o, Jesu sa kọ lati ṣe ileri ijọba Ọrun fun awọn ọmọ Zebede mejeji ṣugbọn jijoko li ọwọ ọtun ati ọwọ osi mi ki i iṣe ti emi lati fifunni, bikoṣepe fun kiki awọn ti a ti pese rẹ silẹ fun lati ọdọ Baba mi wa Mattiu 20 ẹsẹ 20 titi de 23. Njẹ bi a ba ti fi gbogbo agbara fun Jesu kilo ṣe ti ko fi ni agbara lati fi awọn ọmọ Zebede si Ijọba Ọrun tabi gbogbo agbara na din ọsan ni? Jesu ti a fun ni gbogbo agbara laiye ati li ọrun ni o sọ wipe Oluwa mi, Oluwa mi e ṣe ti iwọ fi kọ mi silẹ Marku ori 15 ẹsẹ 34.

Ọrẹ mi ọmọ ẹhin Paul, iran lọwọ wo ni Jesu tun nwa, lẹhin igbati a ti fi gbogbo agbara laiye ati li ọrun fun?

*Wo oju ewe kejo*

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

EYI NI AWỌN NKAN TI YIO ṢELẸ SI Ọ LARIN ỌSẸ YI. OGUN AGBỌTẸLẸ KI I PARỌ

**AQUARIUS (Jan. 22 - Feb 20)** Ti o ba ṣe akiyesi daada, ti o si moju kuro ninu awọn ohun meremere, ni o le bori awọn idasmu ti o wa fun ọ larin ọsẹ yi.

**PISCES (Feb. 21 - Mar. 20)** Nwọn o ba ọ wi fun awọn nkan ti o ko ṣe daada larin ọsẹ yi, maṣe binu si ibawi na, fi tayọ-tayọ gba. ire wa niwaju fun ọ.

**ARIES (Mar. 21 - Apl. 20)** Ṣọra pẹlu ọrọ ẹnu rẹ ki o ma ba kabamọ awọn ohun ti o jade lẹnu rẹ, awọn enia a si sọrọ rẹ laidara.

**TAURUS (Apl. 2 - May 20)** Ṣọra pẹlu iyanjija tabi ija larin ọsẹ yi, ti o ba ja nwọn yio ṣe ijamba fun ọ. Eṣọ di ọwọ rẹ.

**GEMINI (May 21 - June 21)** Ọsẹ yi dara fun ọ lọpọlọpọ, ọrọ idunnu kan yio ṣẹlẹ si ọ, o si ri owo kan gba nibiti o ko lero ṣugbọn ṣọra pẹlu ọrẹ rẹ.

**CANCER (June 22 - July 23)** Awọn idasmu kan wa fun ọ larin ọsẹ yi, ṣọra gidigidi nipa nkan jijẹ, ma si ṣe ba enia ja.

**LEO (July 24 - Aug 22)** Bi iṣẹ ti wulẹ ki o di ẹ lọwọ to, ma a simi daada larin ọsẹ yi, rogbodiyan kan wa niwaju fun ọ, ti o ko ba sora gidigidi, o padanu nkan ti o sọwọn fun ọ.

**VIRGO (Aug. 23 - Sept. 23)** Aṣiṣe kan ti o ba ṣe larin ọsẹ yi yio mu ọ ṣẹ ọpọlọpọ enia, o pade awọn kan ti ẹ ti rira nyin ti pẹ, ẹ sọ dọwọ rẹ.

**LIBRA (Sept. 24 - Oct 23)** Ṣọra lati kẹgan ọmọnikeji larin ọsẹ yi, bi bẹkọ ija nla kan wa niwaju rẹ.

**SCORPIO (Oct. 24 - Nov. 22)** Ṣe gbogbo ohun ti o fẹ ṣe larin ọse yi pẹlẹpẹlẹ, maṣe jẹki ọkan rẹ daru.

**SAGITRAIUS (Nov. 24 - Dec. 22)** Awọn ero ọkan rẹ le ma yọri si rere larin ọse yi, maṣe banujẹ, ṣọra lati ṣe idajọ ti nwọn ba fi lọ ọ.

**CAPRICORN (Dec. 23 - Jan. 21)** Iwe tabi iṣẹ kan ti o ti nreti lati ọjọ pipẹ yio tẹ ọ lọwọ larin ọsẹ yi, ma nireti.

# TANI FẸ KỌ ILE SI ILU-EKO?

EMI FẸ BẸ Ẹ

Awa mba enia ra ILẸ ati ILE, iṣẹ wa si ni lati ba nyin kọ ILE nyin si ILU-EKO ati agbegbe EKO

Eyi jẹ "PEN-SAN" t Olodumare fun ẹ, ati fun Emi na pẹlu.

*ỌJỌ AYỌ NA DE!*

A ki gbe okere mọ didun ọbẹ, Ile labọ isimi oko.
ERE WA NIBẸ, Ẹ MAṢE JAFARA O!
ỌRẸ WA ARAKUNRIN ati ARABINRIN

*Ẹ fẹ ra ILẸ tabi lati ILẸ lati fi ko ILE si ILU-EKO?*

Awa ti wa fun nyin, bakanna ni iranlọwọ wa fun nyin, fun ohunkohun ti ẹ fẹ lati ta, bo jẹ ILE ati ILẸ ni, ao ba nyin ta wọn, bakanna ni ao ba nyin ra ILE ati ILE.

Afani nlanla ni fun awọn ti o ti ni ILE ati ILẸ si ILU-EKO ati AGBEGBE RẸ

Eyi ni lati kede rẹ fun ẹnyin ti ẹ ti kọ ILE wipe:- **E. ADE-GBADEBO & SONS** mura tan lati ba nyin ma a gba owo ile nyin loṣoṣu laitaṣe"

Ẹ dan wa wo, ki ẹ wa wo bi awa tiri; ẹo yin Ọlọrun logo nipa iṣẹ tiwa.

*Ki ẹ fi Stamp Toro (OD) sinu Apo-iwe, fun dida esi Ibere nyin pada. Awa yio si tẹ nyin lọrun pẹlu ogo ti Oluwa.*

**The Manager**
PRINCE E. ADE. GBADEBỌ
29, Adesina Street, Odi-Olowo
Mushin-Lagos.

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

*Lati Ọwọ EJON'GBORO*

### EKO

Ni deede agogo mokanla owuro ni awọn Ọlọpa mu ọdaran kan Sunday Anthony ti o ngbe 11 Ẹpẹ Street nitoripe o ji sile mesan ati kọbọ kan (9/-1d) ti iṣe owo Agbekẹ Samuel ti o ngbe Abari Court.

### EBUTE — MẸTTA

Odaran kan, Alli Maiduguri ti o ngbe 18, Abari Court, l'Eko ni awọn Ọlọpa ti mu nitoripe o ji Bata, ninu ile Nomba 18, Kano Street, Ebute Mẹtta.

### KADUNA

Oniṣowo kan, Cyril Okpara' eni Ọgbọn Ọdun, ti nwọn npe ni Oniṣowo, ni adajọ Kotu sọ wipe ki o lọ si ẹwọn Osu mẹta nitoripe o gba sile merinla lọwọ Malama Ibrahim pe on yio ba ri awọn ẹru rẹ ti o sọnu, ko ri ẹru na bẹni ko da Owo pada.

### EKO

Ni ọjọ iṣẹgun ti iṣe ognujọ osu yi ni gbogbo awọn alapata Eko kọ, ti nwọn kọ si pa ẹran, nitoripe awọn ọmọ jaguda ji egbẹdogbọn poun (£5, 000) mọ Ọga alapata Alhaji Kala lọwọ ni Apapa awọn ole na si ṣe enia meji leṣe.

### EBUTE — MẸTTA

Awọn ọmọde pejọ le iya arugbo kan ti o sọ wipe iya - aje ni on, ti o si nka iye enia ti on ti pa ni orita Ibadan Street ati Nnamdi Azikiwe road ninu ọsẹ ti o koja yi.

Obinrin kan ti o kọ lati sọ oruko rẹ fun Ejon'gboro si mu iya na lọ si ile rẹ.

### NAPLES

Idaamu nla ba gbogbo awọn ero marundinladota ti o wa ninu Ọkọ Oju Omi kan ti nwọn npe ni "Ashanti Palm" nigbati alegun nla kan bẹrẹsi gbe Ọkọ na kiri Oju Omi. Afẹfẹ gbe Ọkọ Oju Omi na kọlu okuta, o si ri sinu agbami Okun pẹlu gbogbo awọn ero inu Ọkọ na.

### ABẸOKUTA

Solomon Ajọse eni Ọdun mẹrindinlogbọn ti iṣe Woli ni awọn enia ti nwa kiri ti awọn ko si ti ri i. Woli na fi ẹsun sun gbogbo awọn Ọmọ Ijọ rẹ 'pe, on fẹ ko iyawo on silẹ awọn ijọ re si ti pari ija na ṣugbọn nwọn ko ri Woli Solomon mọ.

### JOS

Ile mọkanla lo jona tan raurau nigbati ijamba ina kan sele ninu Oṣẹ ti o kọja yi. Eyi ni igba karun ti ijamba ina yio sẹlẹ ni Ilu Jos ninu Ọdun yi.

### EBUTE — MẸTTA

Igba (200) ẹuta ti awọn bisu da iṣe silẹ ti nwọn si bẹrẹsi joko nitoripe awọn nṣe ẹkunwo ni awọn Oniubo oniṣowo Mọto (Mandilas and Karaberis) ti da duro, nwọn si ti fun wọn ni iwe-pe kọ si iṣẹ fun wọn mọ.

### LONDON

Awọn Ọmọ Yoruba ti o wa ni London ti rẹ waya ranṣẹ si Ogbeni T. O. S. Benson Minister eto Irohin ati Eto ikọrọmagbesi wipe ohun ti o ṣẹlẹ si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ko mu, ifọkan bale wa fun awọn ati wipe, o dabi ẹnipe awọn kan fẹ pa Orilẹ-Ede awọn Ọmọ Yoruba rẹ tutapitu.

### FALỌMỌ

Awọn Ọlọpa ti yọ ẹran meji awọn si nwa awọn nnye yoku nigbati ọkọ kenu kan dojude si agbami, ẹniti o wa ọkọ kenu na ti salọ awọn ọlọpa si ti bẹrẹ wa a.

# EYI NI AWỌN ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

## ỌJỌ AJE NOVEMBER 26 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagry |
| ABẸOKUTA | Otta, Atalabi, Sodeke, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Towọbowo, Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnne, Ọkun - Owa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imassi, Owode, |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikole |

## ỌJỌ IṢẸGUN NOVEMBER 27 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja, Agege, Ebute-Ero, Ojo Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajola, Ajegunle, Idogo |
| IBADAN | Lalupon, Ajegunle, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijesha-Ijebu, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijebu-Ijesha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiemi |
| EKITI | Okemesi, Ilaki |

## ỌJỌ'RU NOVEMBER 28 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Sagbe, Ogunjana, Molete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Remo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajola, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Oja - Odan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ NOVEMBER 29 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun - Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku Isabo, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Isara, Imodi, Ishan |
| IJẸSHA | Epe, Iloba, Imuroko, Erinmo Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo—Aiyedun |

## ỌJỌ ẸTI NOVEMBER 30 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Otta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Towọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnne, Ọkun-Owa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imassi, Owode, |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikole |

## ỌJỌ ABAMẸTA DECEMBER 1 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Agege, Ikeja |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajola, Ajegunle, Idogo |
| IBADAN | Lalupon, Ajegunle, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijesha, Ijebu, Isara Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijebu-Ijesha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiemi |
| EKITI | Okemesi, Ilaki, |

## ỌJỌ AIKU DECEMBER 2 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Sagbe Ogunjana, Molete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itamu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Remo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajola, Imesi—Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Oja—Odan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ AJE DECEMBER 3 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Epe |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku Isabo, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Ishan, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Epe, Iloba, Imuroko, Erinmo, Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo - Aiyedun |

